**Ọrọ agba**

ỌPẸRẸKẸTẸ ndagba, Iau adamọ mbajẹ. Otitọ d'ọja o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.

# Irohin Yoruba

NO. 103 WEDNESDAY MARCH 4—TUESDAY MARCH 10 1964 KOBO MẸTA 3D

**AKIYESI**

Awon asoju babalawo Ipinlẹ Iwo Orun ti nwon ti bere ipade ododun won ni ojo ketadinlogbon osu ti o koja ni ilu Ọyọ yio se akanse pataki kan ni ori oke Agidan ni ilu na ni ojo kesan osu yi. "Irohin Yoruba" yio wa nibẹ lati fun yin ni irohin.


# KI ỌBAFẸMI PẸ TITI



OLOYE OBAFEMI AWOLOWO

Orişirişi eto alarinrin ni o ti nlọ lọwọ bayi lati jẹki ọjọ ibi ikarundinlọgọta Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre miringindin ni ọjọ kẹfa osu kẹta ọdun yi.

Ni ọdun ti o kọja, origun mẹrẹrin Naijiria ni nwọn ti şe ajọyọ ọjọ na bi o tilẹ jẹ wipe Oloye Awolowo wa ninu ọgba ẹwọn ni ọjọ na.

Ni ọdun yi, tọkunrin ati tobinrin, lọmọde ati lagba ni nwọn ti fọwọ le tete di ọjọ kẹfa oşu yi.

IBADAN:- Ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre ti lẹ iwe fẹnfẹ fẹnfẹ si arin ilu pe irohin ko ni to afojuba ni aşeyẹ ọjọ na yio jẹ.

Bakana ni awọn akẹkọ ni ile ẹkọ nla Unifasiti Ibadan ati Ifẹ ti nşe eto lati jẹki ọjọ na kọyọyọ.

Onirohin wa kan fi imu fịlẹ gbọ pe gbogbo awọn ọjọgbọn imọ ijinlẹ ka-nka-kn-nka, awọn akẹkọ ni awọn ile iwe nla na ati gbogbo ọmọ ẹgbẹ Afenifẹre ni ilu Ibadan ati agbegbe rẹ yio pejọ si ile Oloye Awolowo ni Oke Ado lati şẹ aşeyẹ nla kan. Ara awọn enia ti yio sọrọ nibẹ ni ọj gbọn Dokita Victor Oyeunga, Dokita Samuel Aluko ati Alhaji D. S. Adegbenro.

IKỌLE EKITI:- Awon ọmọ ẹgbẹ Afẹnifere yio jo kakiri igboro.

EKO:- Igboro Eko yio lọ lu ni ọjọ na fun asey pataki ti awọn Ẹgbẹ Afẹnifere yio şe fun ọjọ Ibi Oloye Awolowo. Ilu Eko fẹ fi ijo ati orin pẹẹta ni ọjọ na.

Bakanna ni awọn ilu miran tun nmura lati jẹki ọjọ na yatọ si gbogbo ọjọ.

Fun irohin ati aworan ọjọ ibi na, mura silẹ lati ka 'Irohin Yoruba' ti o ga ju gbogbo awọn iwe irohin iyoku lọ.

## Ọrọ Olotu

### BARIKA FUN ỌJỌ IBI

NI ọtunla ti işe ọjọ kẹfa oşu kẹta ọdun 1964, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, ọkanşoşo ajanaku ti nmi igbo kijikiji, yio di ọmọ ọdun marundinlọgọta. Aja ti o ba re ile ẹkun ti o bọ, o yẹ ki a ki ku orire. Ẹniti ko ba şẹku, ti ko ba dagba iya, yẹ fun apọnle gidi.

IDI eyi ni a fi fi tọkantọkan ki Baba 'Layinka pe o ku orire. O ku ifarada ati ifaiyagba nitori awọn mẹkunnu. Ori awọn mẹkunnu ti o nja fun ko ni şai duro ti ọ. Ori awọn abiyamọ ati agbẹ ti o nja fitafita fun ko ni fi ọ silẹ loju ogun ti o wa. Awọn orişa Yoruba yio fun ọ lokun lati jagunmolu.

CẸCẸ bi ẹlẹran ara, o şeeşe fun Oloye Awolọwọ lati ro wipe ọgba ẹwọn ti jẹ ni igbesi aiye on. Ki a ran Oloye Awolọwọ leti pe tirẹ kọ ni ekini ninu awọn aşiwaju nlanla ni agbaiye, tirẹ kọ ni yio si jẹ opin. Bi a ba ranti awọn akọni aiye bi Mahatma Ghandi ti ilẹ India, Pandit Nehru, Olotu Ijọba ilẹ India loni; Dokita Kwame Nkrumah, Arẹ ilẹ Ghana loni; Ẹni ọwọ Makarios ti ilẹ Cyprus; Alagba Jomo Kenyatta, Olotu Ijọba Kenya loni; Alagbara De Gaulle ti işe Arẹ ilẹ Faranse loni ati awọn enia miran ni agbaiye, Oloye Awolọwọ gbọdọ ki ara rẹ ku erire pe on ko waiye lasan. Jesu Kristi şa ku laişẹ şugbọn nitori igbala ọmọ araiye.

O JẸ idunnu fun wa pe Oloye Awolọwọ ni ifaiyabalẹ ju awọn enia miran ti o wa lẹhin ọgba ẹwọn lọ. Awọn enia miran ko le jade laijẹ wipe awọn ọlọpa gbe ibọn siwaju ati ẹhin wọn. Nwọn da ẹgbẹ silẹ şugbọn araiye ko gbaa lọwọ wọn. Kini ireti wọn? Nwọn njẹun pẹlu ifoiya ati okunkun biribiri niwaju wọn. Ẹhin wọn ha le dara bi? O şeeşe fun awọn ọta Oloye Awolọwọ lati maa yọ ninu ara wọn pe ọwọ wọn ti tẹ ẹni ami ororo na bi awọn ọta Jesu şe dunnu ni ọjọ wọnni şugbọn ki nwọn ranti pe Oloye Awolọwọ nlo igbesi aiye rẹ gẹgẹbi Ẹlẹda şe kọwe rẹ. Ohun kan ni a mọ pe awọn amọnişeni ati apanimayọda ti nwọn jẹ ajara kikoro, ẹnu wọn ati ẹnu ọmọ wọn kun.

A MỌ dajudaju pe ayọ gbọdọ kun inu Oloye Awolọwọ nisisiyi nitoripe o nja fun ohun ti o gbagbọ yatọ si awọn enia melo kan ti nwọn nja fun owo ati ipo. Ki işe wiwa si aiye ni o şe pataki bikoşe ohun ti enia wa şe laiye. Bi Jesu Kristi şe wa si aiye lati wa gba ọmọ araiye la ni Judasi wa si aiye lati dalẹ nitori ọgbọn owo idẹ fadaka. Iparun ni o kẹhin Judasi nigbati ayọ kẹhin Jesu, ti orukọ rẹ si di konigbagbe. A kesi Oloye Awolọwọ lati ranti pe igbẹhin ni alayo nta. Bi ẹmi ba mbẹ, ireti mbẹ pẹlu.

ỌPỌ ọrọ ko kun agbọn. A wi fun Oloye Awolọwọ pe, bi ẹkun ba pẹ titi di alẹ, ayọ yio wa ni owurọ. Bi o pẹ, bi o ya, ogun ọdun yio ku ọla. Tẹni bẹgi loju, igi a ruwe. A bẹ Ọlọrun pe ki o da ẹmi Oloye Awolọwọ si. Ki Ọbafẹmi pẹ titi, da Awolọwọ si. Irohin Yoruba sọ pe kabiyesi, ayanfẹ Oduduwa; aşeyi şamọdun.

## Awọn ọjọ iranti fun Awo

1 Ọjọ Karundinlogbon oşu karun ọdun 1962 (25: 5: 62) awọn omolehin Oloye Akintola da ija sile ninu Ile Igbimo Aşofin Iwọ Orun Naijiria.

2 Ojo kokandinlogbọn oşu karun odun 1962 (29: 5: 62), Ijoba apapo kede ofin idagiri lori Ipinle Iwo Naijiria. Awọn asiwaju egbe Afenifere gba iwe ihamọ – Oloye Awo lọwọ lọ si Ikenne.

3 Ọgbọn ojọ osu karun 1962, (30:5:62) Alakoso Idagiri de Ibadan lati Eko,

4 Ọjọ kọkandinlogun oşu kefa odun 1962 (19:6:62) nwon fun Oloye Awolowo ni iwe ihamọ lati lọ si Lekki

5 Ni ojo karun oşu keje ọdu 1962 (5: 7: 62) Oloye Awolowo pada lati okun Lekki si Ikenne,

6 Ojọ kọkandilogun osu keje odun, 1962 (19 :7: 62), Oloye Awolọwọ gba iwe ihamọ ni agogo mẹfa ku işẹju marundinlogun lati lọ si nọm a 7 Bell Avenue, Ikoyi.

7 Ojọ kejilelogun osu

Wo oju ewe kẹjọ

